# A jẹ ẹni ti kii ka omi ti awọ rẹ f'ara pẹ dúdú, ati omi alawọ iyeye lẹ́yìn imọra si nǹkan kan

Lati ọdọ Umu ‘Atiyyah - ki Ọlọhun yọnu si i - o jẹ ẹni ti o gbe adehun (ibura) fun Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a -, o sọ pe: A jẹ ẹni ti kii ka omi ti awọ rẹ f'ara pẹ dúdú, ati omi alawọ iyeye lẹ́yìn imọra si nǹkan kan.
[O ni alaafia] [Al-Bukhari with a similar wording]

Saabe lobinrin Umu ‘Atiyyah - ki Ọlọhun yọnu si i - sọ pe dajudaju awọn obinrin ni igba Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - o ki n ka omi ti o maa n jade ni oju ara obinrin- ti awọ rẹ f'ara pẹ dúdú, tabi awọ iyeye - lẹyin riri imọra nibi ẹjẹ nǹkan oṣu: wọn o ki n ka a si ẹjẹ nǹkan oṣu, nitori naa wọn o ki n fi irun ati aawẹ silẹ nitori rẹ.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/10014